# AKIYESI KINI

TI ỌJỌ KEJIDINLOGUN OṢU KEJE ỌDUN 1955

## NINI ATI FIFI ILE FUNNI

### NI AYIKA IBITI IJỌBA ILEṢA TIJẸ ALAṢẸ

Eyi ni lati ṣe ikede si etigbọ gbogbo enia pe Igbimọ Ijọba Ileṣa pinu ni ipade kan ti wọn ṣe ni Gbọnga Obokungbusi ni Ileṣa, ni Mọnde ọjọ kejidinlogun oṣu keje ọdun 1955 pe a ni lati fi si etigbọ olukuluku nipa ikede yi pe a ti nṣe ofin lori nini ilẹ ati fifi ilẹ funni lati kọ ile gbigbe tabi ile iṣiṣẹ. A nṣe ofin na fun anfani awọn ọmọ onilẹ ati awọn alejo to ngbe ni ayika ibiti ijọba Ileṣa ti jẹ alaṣẹ.

EKEJI:- A pin ilẹ to wa ni ayika ibiti ijọba Ileṣa tijẹ alaṣẹ si ipa mẹta, bayi:

(ipa kini) Ilẹ to jẹ ohun ini ti ẹnikọkan.

(ipa keji) Ilẹ to jẹ ajọni gbogbo ilu:

(ipa kẹta) Ilẹ to jẹ ti idile oye.

A tun pin Ilẹ to jẹ ti idile oye si isọri meji:-

(Ekini) Ilẹ ti idile Oye alakujogun.

(Ekeji) Ilẹ ti oye ti ki i ṣe alakujogun.

ẸKẸTA:- Nipa ti ilẹ to jẹ ohun ini ti ẹni kọkan, iba ofin to wa larin ẹni to nta ati ẹni to nra lo wa lori rẹ. Ṣugbọn ni awọn igbati ijọba ti nmura lati ṣeto igbekalẹ bi wọn yio tiṣe ma kọle fun gbigbe ati fun ṣiṣiṣẹ larin Igboro, olukuluku ni lati yago fun ilẹ didura ki ẹlomiran ma ba ra ilẹ tiko ni le lo nitori eto igbekalẹ ile kikọ na.

ẸKẸRIN:- Gbogbo awọn ajọni ilẹ to wa ni ayika ibiti ijọba Ileṣa tijẹ alaṣẹ, to wa ni abẹ itọju Ọba Ọwa gẹgẹbi aṣa ibinibi fun anfani gbogbo Ijẹṣa ni lati wa ni abẹ itọju Owa ati ijọba Ileṣa.

ẸKARUN:- Ẹnikẹni to ba fẹ ẹtọ lati lo ilẹ ajọni ni ayika ibiti ijọba Ileṣa tijẹ alaṣẹ ni lati kọwe si ijọba Ileṣa. Ọwa, Alaga igbimọ ati akọwe ijọba Ileṣa ni yio ma fọwọ si iwe lorukọ ijọba Ileṣa si ilẹ ajọni ti wọn ba yọnda fun ẹnikẹni:

ẸKẸFA:- Ẹnikẹni to ba nfẹ ẹtọ lati lo ilẹ oye alakujogun ni lati lọ ba ẹniti o wa lori oye ni asiko na, On ni ẹniti o ni lati yọnda iru ilẹ bẹ fun ẹniti o fẹ, ṣugbọn o ni lati jẹ pẹlu imọ ati ifọwọsi olori idile kọkan ninu awọn idile ti ijọba Ileṣa mọ pe o lẹtọ lati gori oye na. Iwe adehun ti wọn ba ṣe lori ilẹ bẹ, ẹniti o jẹ oloye to wa nigbana yio fọwọ si, olori idile kọkan to lẹtọ lati gori oye na yio si fọwọ si pẹlu. Ẹda awọn iwe adehun bẹ ni lati dọwọ ijọba ki kikọ ile sori ilẹ bẹ to jẹ gbigba.

EKEJE:- Ẹnikẹni to fẹ ẹtọ lati lo ilẹ oye ti ki i ṣe alakujogun ni lati lọ sọ fun ijọba ko si tọka adugbo ti ilẹ na wa. Ijọba yio dari rẹ sọdọ oloye to wa ni itọju ilẹ na, oloye na ni yio sọ boya ẹnikan ti wa lori ilẹ na tabi kosi. Oloye na ati ẹni na yio ni ipinu lori iye owo ilẹ na (ijọba le ṣe ayipada). Ẹni to fẹ ilẹ na yio wa ṣe iwe adehun eyiti oloye na, Alaga igbimọ ati Akọwe ijọba Ileṣa yio fọwọ si. Ikojọ ohun to ba ti ibẹ jade yio jẹ pipin larin oloye na ati ijọba. Oloye yio ko ipin kan, ijọba yio ko ipin meji, Iwe adehun ti wọn ba ṣe bi eleyi fọwọsi yio wa ni ikawọ ijọba ki ile kikọ sori ilẹ bẹ to bẹrẹ.

ẸKẸJỌ:- Gbogbo eto lori ọrọ ilẹ to ni ifihan nipa iwe adehun ti wọn tiṣe pẹlu awọn oloye alakujogun, awọn oloye ti ki ṣe alakujogun tabi awọn to ti joye siwaju wọn, ti wọn ti fọwọ si, ti o si niye lori ni ao yọ kuro ninu eto titun yi.

ẸKẸSAN: Nigbati ijọba Ileṣa ba pari awọn ofin lori nini ati fifi ilẹ funni ni igboro Ileṣa, ao gba ifaramọ ijọba Ẹkun Iwọ Orun Naijiria pe ki ifẹsẹmulẹ ofin na bẹrẹ lati ọjọ kẹtadinlogun oṣu keje ọdun 1955.

**Babatunji Olowofoyeku**

Alaga ti Igbimọ Ijọba Ileṣa

Urban District Council Office,
Ilesha, Nigeria, 18th July, 1955.

## ITỌJU ỌNA IGBORO ILEṢA

Ogunlọgọ enia lo ti nkọwe nipa atunṣe adugbo yi tabi adugbo yẹn jakejado igboro Ileṣa. Ni idahun si awọn itọkasi wọnyi ijọba ti ṣeto, wọn si fun wa ni ikede yi lori bi wọn tiṣe ṣe leto na. Wọn ni:—

"A ti pin ilu Ileṣa si ọna mẹrin, a si fi abojuto ọna igboro gẹgẹbi a ti ṣe pin le awọn olori alabojuto iṣẹ igboro mẹrin lọwọ. A si ko awọn lebira mejilelọgbọn fun awọn olori Iṣẹ mẹrin na lati ma lo fun atunṣe ọna igboro.

"Kọmiti to nṣeto lori iṣẹ igboro sọrọ lori eto yi ni ipade ti wọn ṣe ni ọjọ kẹrindinlogun oṣu May 1955. Kọmiti na ronu si pe nṣe loyẹ ki wọn yan awọn Kansẹlọ kan lati ma ṣe abojuto awọn iṣẹ igboro na bi wọn ti ṣe pin wọn. Nwọn ni iru awọn Kansẹlọ bẹ yio rinmọ awọn Ọga iṣẹ ati awọn lebira wọn lati ripe iṣẹ nlọ dede.

"Ni iyọri, wọn pin iṣẹ igboro sọna mẹrin wọnyi pẹlu awọn Kansẹlọ ti yio maṣe abojuto iṣẹ wọn"

Ipin kini ni Odo-Agbẹdẹ, Ereja, Oke-Iyin, Oke-Ẹsẹ, Ayesọ, Isọna, Ijofi, Orogba, Odo-Iro, Iṣida ati Odo Ẹsira. Awọn adugbo wọnyi wa labẹ itọju awọn Kansẹlọ E. M. Ogunbiyi ati Shewu Arowojọbẹ.

Ipin keji ni Iṣokun, Ikoti, Igbogi Ọmọfẹ, Idasa, Ikoyi Aragan ati Oromu. Wọn wa ni itọju awọn Kansẹlọ M. A K. Ẹsọ ati Jonathan Oyedeji.

Ipin kẹta ni Itakogun, Ẹgbẹidi, Ibọsirin, Isinkin, Iwere Orikinran, Ijọka, Ifọsan, Oke-Ẹsọ. Wọn wa labẹ abojuto awọn Kansẹlọ Gabriel Ẹsọ ati I. O. Odẹyẹmi.

Ipinlẹ kẹrin ni Oke-Oye, Ifọfin, Ilọrọ, Anaye, Idifi, Iroye, Idio, Isale, Okeṣa, Ilẹmọ, Imọ, Igbaye, ati Itinsin. Awọn na wa labẹ itọjuto awọn Kansẹlọ M. I. Ekundare ati J. O. Ogundipẹ.

## RAFFLE DRAW

**You are hereby notified that owing to the late arrival of the full quota of Raffle Tickets, the draw for prizes has been postponed from Friday 5th. August to Friday 19th. August 1955. The Draw will take place at the same place on 19th. August at Council Recriation Ground Oshogbo Road Ilesha at 4 p.m. on 19th. August.**

**You are notified that a correct list of winning ticket numbers will appear in Irawo Ọbokun issue of Monday 22nd. August 1955.**

**WO AWON NOMBA TO JAYO BOIRE NINU IWE TI 22/8/55**

Printed and Published by Ijesha Press Ltd., B149 Okesha Street, Ilesha 8 - 8 - 55